Chief Secretary to the Government

# EKO AKETE.

"Emi yio fi ohun ti o ndun Makunnu han awon Alagbara, Ngo si je Alagbawi awon Odi."—W. T. Stead

Vol. VI. No. 292 SATURDAY, SEPTEMBER 15, 1928 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

## White's Radical Gonkiller.

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs**, and sold only by

Victor White, Esq., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

Price: **Ten Shillings (10/-)** per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Ilakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si nję ki o ri aye wu arun mi silę.

CHIEF SEC. 20 SEP. 1928 LAGOS

Aperis
Nir Adeoshin



LOOK FOR THE PORTRAIT OF
Dr. Earl S. Sloan
SLOAN'S
N&B
FAMILY
LINIMENT
Trade Mark Registered
KILLS PAIN
RELIEVES
Rheumatism
Neuralgia
Sciatica
Sore Gums
Sore Muscles
Sprains
Strains
Swelling
Tender Feet
Toothache
Ulcerated Teeth
Stiffness and Soreness after Severe Exercise
General Directions for External Use
Apply Sloan's Liniment freely, rub very lightly
Keep away from Fire or Flame
mists and Patent Medicine Dealers
Carton adopted 1916.
s for Great Britain
FASSETT & JOHNSON.
Road, London, E.C.
RED ONLY BY
rl S. Sloan
CORPORATED)
ST. LOUIS. TORONTO. CAN.
ome Office. BOSTON
in United States of America
TO
STOP YOUR
ACHES & PAINS
SIMPLY USE
SLOAN'S LINIMENT
Sold by all Dealers.
Wholesale Fassett & Johnson Ltd
Clerkenwell Rd London.
England

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILĘ NI OWO GBIGBA RE.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oșu męfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oșu męta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ę fi owo ati *Letter* ranșę si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### INA GORI ILE FĘJU.

Ina kan șęlę ni alę *Monday* ọsę yi niwọn agogo męsan abọ ni Ęlęgbata, wara were nwọn ti pa ki o to șe jamba pupọ.

### DUNIYAN—LABARI.

[ LATI ỌWỌ KEKERE-AWO. ]

### IPADE-GBOGBO-GBO.

Nwọn șe ipade Gbogbo-gbo ti awọn ęgbę Dęmọ ni Ile Afari-ogun ( G.M.H.) ni ọjọ Satide to kọja ti nșe ọjọ kęjọ oșu yi, labę Alaga Ọlọla Loya Eric. O. Moore ati awọn ojoye onifila funfun ati awọn Abagbọn, ni agogo męrin irọlę titi di iwọn agogo meje ku ișęju męwa.

Nwọn tun fi ipade Gbogbo-gbo miran si Satide ti oni yi, gęgę bi Alaga wa ti wi fun gbogbo ọmọ ęgbę.

### HU......U HA HA !

Igbe yi lo fęrę jọ igbe ti obinrin obiobio kan nke nigbati a gbo wipe awọn "Meriwo" awọn ọmọ jaguda pali baba bilisi pa a lara pọnwn kan ni ọjọ Satide ijęjọ ni Ereko, anu obinrin na șe ęnikęni jọjọ ęnikeji tobę ti o ję wipe bi ęlomiran ni agbara owo na o le fun obinrin yi ; wayi o kini a ti ma șe ti awọn ọmọ 'ta wọnyi si lojojumọ bayi ?

### ĘGBĘ SERAFU.

Awọn ęgbę Serafu itafo wasi kan ni Egerton Road, ni alę ọjọ Satide to kọja, nșe ni gbogbo wọn akọrin ti baba oni-wasu wọn nșe bi alara-kunmọya.

### ADU ATI ỌLỌPADE STREET.

Awọn adugbo mejeji ti a daruko wọnyi le șokunkun pupọ to bę ti enia ki ifi saba rin tobę lapa ibę lalalę, a le sọ wipe aseko eșupa nikan ni nwọn o ma ri anfani nina 'ju ję, ati pęlu eyi kọle fun awọn ara adugbo na ni iwuri tobę lati ma ję faji lojude wọn bi awọn adugbo miran ti o ni anfani ina Ọba lode. Nitorina iba dara dię bi awọn Ijọba ba le fun awọn adugbo mejeji na ni anfani ina ode, tabi bomiran ti o tun yę bi adugbo Evan Street, nitori jamba ti ole ti ma bę ninu okunkun.

### ĘGBĘ DĘMỌ

Ohun pataki ti awọn ęgbę Dęmo sọrọ le lori julọ ninu ipade wọn ni ti ọran ibo didi fun awọn Așoju męta ti Eko, ti nwọn yio ran lọ si Igbimọ Așofin, eyiti nwọn yio șe ni ọjọ kejidinlogbon oșu yi, bi nwọn ba ni o di ọwọ Imale, awọn Imale kę a ni o dọwọ Soko, ę mașe jafara o, nitori afara ni ija ękun, ki Oluwa ma ję ka ri dasi o !

### "DAILY TIMES."

A ko tilę mọ awọn ęniti o kuku joye kowe-kowe si inu iwe- ojojumọ ti nwọn tun ni suna *Daily Times* nisisiyi, bi olotu iwe na lo ndabira ki a ma kọ iwe męșași nipa Ọgbęni Makoli bi o si șęșę gba awọn akọwe kọwura sidi ișę iwe wọn na ni a ko mọ ? Ọrọ Ọgbęni Makoli ti iwe na kuku fi nșe ișę șa nigbagbogbo lati ęnu ọjọ męta yi wa lo mu wa bere. A ko le ba ọbọ jawura ri i o tunbọ jęki o wọ iwe yi lewu, lori gbogbo rę julọ, o yę wipe ki a mọ wipe ọmọde ti o bu iroko si o boju wẹ ęhin ni ti won ję, ęru ti ọko ru ti, ti o fọ lori, ori lasan ni on yio fi ru, nję ori na ki yio lo tutu bi elubọ ? o di igbę na, ęnu rę la kosi wayi, ki akọwe kọwura na tunbọ tęnu gege rę ati tadawa rę șe daradara, așọ mbọ wa și mọ egungun loju ęnikeji bi Ọlọrun fę.

### SUMỌNU AȘOROBI

Gbukę li a gbo ti iku Ọgbęni ti o nję Sumọnu Așorobi ni ile rę ni ęhin ọ a Ereko lọjọ Sunday ijeje—ki Oluwa dęlę fun u o, ki o si șe ęhin rę ni rere.

### MUNISIBA ATI ILU.

Ọpolọpọ ile ni awọn Munisiba npa lașę ki nwọn ma tunșe laseko yi fun itori ilera-ilu papa nitori ajakalę-arun ti o mbę larin ilu yi loni, nipa eyi o si

ṣọ awọn ile gbogbo na di afinju, dajudaju eyi dara pupọ.

Ṣugbọn ohun ti awọn Munisiba iba ṣe ti o yẹ loju wa nipa inawo abaradi ti ẹlomiran nṣe se ori titun ile wọn ṣe na gẹgẹbi aṣẹ ti awọn Munisiba nfun wọn, nitotọ nwọn nfun wọn ni aseko gigun daradara, eyi ko to sibẹsibẹ, bi nwọn ba fẹ ṣe daradara julo ni, Munisiba iba ma fun wọn ni c. o d ẹdiẹ gẹgẹbi irànlọwọ nitori awọn mẹkunnu, ẹlomiran wa bi nwọn tilẹ fun ni akoko gigun lati fi tun ile rẹ ṣe, ẹna ti yio ma wa kirakita ni wipe ki Ọlọrun le bo on ni aṣiri owo ti inawo ile na jẹ ki on ma ba tẹ aṣẹ awọn Munisiba leti, bi ẹlomiran yio lọ wa owo t rẹ ya kona-kọna nko, gbese kan ni iyẹn, ọpọlọpọ ẹlomiran lori ipo ti ile on wa ti o si nfẹ tunṣe bi o ti tọ loju on papa, ṣugbọn nigbati aye rẹ ko si ko jẹki nwọn le ri owọ yọgbe, eyiti awọn Munisiba papa si npa laṣe pe ki nwọn ma tunṣe ni apapandodo fun anfani awọn onile ni, nitorina li a fi sọ wipe awọn Munisiba iba ma ṣe atilẹhin owo diẹdiẹ si i fun wọn.

## INA PUPA BẸLẸJẸ.

Ni alẹ ọjọ Monday ijẹfa ni arakuyamu ina kan ṣẹlẹ ni Olowogbowo ni Apongbon Street, ni ẹhin kule ile Alapafuja tabi Baba dudu ni iwọn agogo mẹsan titi de agogo mẹwa, awọn panapana Ọba ṣe iṣẹ wọn pe perepere nwọn si pa banbari ina na mọlẹ pirapira.

Wayi o, aṣa wo ni ki ina ma jo nibikan, ki gbogbo ero si ma rọ lọ si ibẹ bi eyiti o un wọ lu njẹ gbogbo awọn ẹniti o kuku nba aniyan, ajo lo lo kuku npọ to re yen tobẹ ti gbogbo wọn a si ma pa ariwo ge ? ọkan ẹni ni alufa ẹni, ki olukuluku toju aniyan rẹ daradara, nitori awọn alaniyan buburu ọjọ kan ki idara fun wọn.

## O DA BỌ.

A gbọ wipe Loya W. Wells-Palmer ba ọkọ *Aba* ti o ṣi nihin ni ọjọ Jimọ ijẹsan lọ si ilu oyinbo—ọna 're o !

## Ẹ KU ABỌ.

A gbo wipe Ọlọla Gomina Graeme Thomson, K.C.B., G.C.M.G., ati aya rẹ ti de ni Monday lati ẹna irin-ajo wọn ti nwọn ti lọ lati ọjọ kokandinlogun oṣu August to kọja.

## IYA-AFIN AJARATU ILORI.

Gbukẹ ni a gbọ ti iku Aja atu Ilori ti o ṣẹlẹ ni ile rẹ Koilọ Street, ni Isalẹ-gangan ni oru ọsẹ ijẹjẹ mọju ọjọ Atọni, nwọn ṣe isinku rẹ si Itẹ Oke Suna. A ki Lemomu Jinadu Mati, Disu Giwa, Asani Ṣekoni ati awọn jakanjakan nwọn ku ọfọ, ki Oluwa dẹlẹ fun u o !

## BARIKA O!

A ki Ọlọla Samuel Wilson, K.C.B., K.C.M.G., nwọn ku abọ idalẹ ti nwọn ti lọ, alafia kọ li ẹ de bi.

## AJAIBA!

A gbọ wipe ẹnikan wọn ẹran ewurẹ kan lati adugbo Ẹpẹtẹdo si apa adugbo Oluwọle, nigbati ẹran na si tu kun, o si ṣi o fori le ibiti nwọn ti nwọn, tabi mbọ lati odidi Oluwọle si Ẹpẹtẹdo, lai ṣi 'na lai ṣe kan—eyi ara !

## ILU KOMITI.

Awọn Ilu Komiti ti Dẹmọ ṣe ipade kan ni Ehingbẹti ni irọlẹ ọjọ *Tuesday* ijarun, ati ni *Wednesday*, nwọn ṣe ohun pataki nipa awọn mẹta ti nwọn nfẹ mu lati dibo tun lọ si Kansulu—Moore, Jones ati Doherty.

---

## "NIGERIAN DAILY TIMES" ATI ỌGBẸNI HERBERT MACAULAY.

Gẹgẹ bi mo ti nba irohin mi bo lati ọsẹ to kọja—ko si ẹnikẹni to ma wipe gbogbo bi ọro ilẹ yi ti nlo si, ohun ko mọ, yala ẹru ilu yi ni, alejo ilu yi ni, ọmọ bibi ilu yi ni, gbogbo wa patapata lo mọ nkan to nlọ ni ilu yi.—ki ama ba ọrọ wa bọ. Nipade ti Ẹgbẹ Dẹmọ ti ijẹjọ, ko si ẹniti ẹnu ko ya bi ẹgbẹ na ti kun to, ti ero gba ile ati ita kan, ti ẹsẹ ko gbeji ni, ṣe gbogbo enia patapata ni ilẹ yi, lo mọ ore ti ẹgbẹ yi nṣe fun ilu wa yi, ṣugbọn ọpọlọpọ enia lo nfi ẹnu ṣata ẹgbẹ yi wipe Dẹmọ ti fọ, lẹhin ti wọn ti mu olori wọn—gẹgẹ bi ati sọ ni ọsẹ to kọja, awọn ti irufẹ ọrọ bayi njade ni ẹnu wọn, were patapata ni wọn nṣe, osi to asiko ti ani lati mu wọn lọ si Yaba ki wọn wo wọn. Nigbati Alaga ẹgbẹ yi Ọgbẹni E. O. Moore Aṣọju wa ri Igbimọ Aṣofin kesi ọmọ ẹgbẹ nipa owo dida ṣile meji meji ẹni kankan, ṣiba ṣiba lori tabili Alaga kun fun owo yi. Ni apo ti owo yi ti jade, ki Ọlọrun ko bu si apo olukuluku yin, Ẹgbẹ ko ni tu, kikun lo ma kun. Asi ki gbogbo ẹgbẹ Igbimọ ati awọn Oloye wọn ku ko kari. Ọlọrun a fun yin ṣe.

Gbogbo wa lori ka ninu iwe irohin Daily Times nipa igbesi aiye ọgbẹni wa kiniun enibudo Herbert Macaulay C.E., ẹniti o wa nipa mọ loni yi, ti olotu iwe irohin Daily Times si sọ fun gbogbo aiye mọ ohun ti oda ohun pelu ijoba pọ. O dara pupọ fun irufẹ iwe bẹ lo tẹ si ode, awọn agbalagba lo ma npa lowe wipe agbalagba ki wa loja ki ori ọmọ titun wo. Owe ni o—ṣe olotu iwe irohin yi ni awọn agbagba lẹhin ti wọn ma nba ji rero ohun to ni lati ko, gẹgẹ bi aṣa awọn alagbawi wọn wipe ha ! Olotu iwe irohin yi, ki fi han ẹni ẹni ko to ko en to ba wọn eyi le jẹ otọ, o ku wọn pelu ara wọn, yala ofi iwe yi han wọn, yala ko fi han wọn ọrọ kekere ni yen niwaju wa, nitori pe, ki ṣe gbogbo wa lo mu ọmu iya wa dagba, ki si ṣe gbogbo wa ni Baba ati Iya ko dajudaju. Bọwọ fun Baba on Iya rẹ, ki ṣe Baba ẹni nikan, ṣugbọn ṣe ẹniti o ba ni Baba ati Iya ni yen to si jẹ anfani wọn, iyẹn lọ le mọ ọwọ ti wọn nbu fun

Baba oni Baba, ọpọlọpọ lori iṣẹ ninu aiye, orişirişi iya ati işẹ lo si wa, şugbọn bi okun ba mu ẹlomiran tan, ko si iwa ti ko le hu lati juba fun ẹniti oba julọ, nigba na lo ma mọ ọwọ agba, wipe ni tilẹ tọlọrun lati ijọ ti wọn ti da iran awọn eleyi si aiye, ni wọn ti ju awọn iran ti Baba to fi de Baba nla on lọ, şugbọn nigbati irufẹ awọn kobokobo tabi awọn Dewo tabi awọn kinakuna tabi awọn onihoho ba wọnyi ba de ipo ti Baba nla wọn ko de, wọn a gbagbe ara wọn, ko si si ohun to mu irufẹ eyi wa ni wipe awọn ọmọ wa papa ni wọn ngbe irufẹ awọn kini wọnyi lehin ni wọn wa fi nbu wa jẹ, ogo kọ ni fari wọn pọ, to bẹ gẹ ki wọn to mu gege wọn, lati ma kọ ikọkukọ, lati ma sọ ohun ti ko si lẹnu wọn, şe ọrọ si sọ yi, o dara fun ẹniti ẹnu rẹ ba kere, şugbọn ẹwo ẹnu ọga wa, ẹ ori wipe o tobi ju fun ohun to sọ, nitori na ki şe wipe ohun to sọ buru ni ọna keji, ewo ni wọn ma fi dara ya fun ara wọn, ti inu wọn si ma ma dun, wipe awọn şe nkan gunmọ, ohun ti awọn şe si dara—ko si ọmọluwabi to ma fẹ ko irufẹ bẹ nilẹ yi, ti ọwọ rẹ ko ni gbọn. Şugbọn Ğbogbo awọn nkankinkan wọnyi. Ẹ ba mi gbe jingi, ki ẹ fi wo wọn wo, orişirişi ni wọn jẹ, omiran ninu wọn nşe abẹsẹ fun ọmọ inu rẹ nitori ipo to wa wipe on ko le de irufẹ ipo bẹ mọ, abẹyọ to si nşe ki şe wipe fun ẹkọ pataki kan bi ko şe fun ọtẹ tabi tẹmbẹlẹkun, ko si ibi ti eşe ko si, awọn ẹnibẹ ni wọn nşe irufẹ nkan bẹ, ko si le le wun wọn, ọpọlọpọ ni wọn ti palaro arẹdu, omiran ti wọn ti palaro Ọba aro dudu daradara lọwọ Baba rẹ, ki ni ẹnikan şe ti Baba ẹlomiran ninu yin ko ti şe ri, ẹ joko si ẹnu mimi, ẹlomiran ati wọ ẹwọn ni ati kekere şugbọn ti awọn ẹdọmọkunrin wa ba nwo wọn, aşe bi ko si alebu kan lara wọn, ẹni mimọ lo ma ma pe wọn. Şugbọn bi agbalagba ba pe wipe ẹni ti ori yẹn kini fari rẹ, ọgba ẹwọn ni wọn bi si, tabi Baba rẹ ẹlẹwọn ni, tabi on papa agaga ki ni fari wọn, ẹ ma fi ọrun yọ mi gbogbo wa lo jọ nlọ bi ọran ogba ẹwọn kọ, ẹ ma jẹki alebu ẹnikẹni ma gbo si ẹnu yin mọ, nipa ẹnu yin ni ao da yin lẹjọ ni ọjọ miran.

Ẹ tun ba mi wo wọn wo, ẹlomiran a ma sọ wipe Ọgbẹni Herbert Macauley C.E., ti fi ẹnu rẹ ba on jẹ kiri ilu, on ni ko jẹ ki ọla ati ọwọ ti awọn ara ilu nfun on ko po si mo, otọ ni eyi şugbọn ọla ati ipo ti iwọ nwi yi, bawo ni iwọ papa ti rin si ninu igbesi aiye rẹ, iwa rẹ wo lo mọ, bi aba gbe jingi wo pupo ninu aşelu wa, ọpọlọpọ lo ni alebu tirẹ, alebu ẹnikan o yatọ si ti ẹnikeji, bẹni ninu ẹgbẹ kanna ni wọn wa, ni ọna kanna ni wọn nrin, ẹlomiran ko bi ọmọ şugbọn iwa ọdaju iwa ika lati kekere rẹ si wa ninu rẹ, osi ti ro pin wipe on to wu ki on ko şe ni aiye ko si ẹniti wọn ma gba ẹsan ni ara rẹ o wa gbagbe wipe ohunkohun ko wu ki aşe ninu aiye, ao jihin rẹ ni ọjọ kan, ẹlomiran to si bi mọ kẹ, on na ani oro ninu bi ọka, şugbọn awọn ọmọ rẹ wa mu ọna ti wọn pọn, nitori awọn fẹ tun orukọ ara wọn şe wọn ko fẹ tẹlẹ ọna ti awọn obi wọn nhu, ki wọn ma gbẹsan rẹ ni ara wọn ni ẹhin ọla, omiran kẹ to jẹ wipe awọn obi won orukọ wọn ko de ẹhingbẹti to jẹ wipe anu Ọlọrun lo gbe awọn ọmọ dide ti orukọ gbogbo iran na fi han, ngbo ẹyin ti Ọlọrun gbe dide nkọ iwa kini ẹfi ipo ua hu, ọmọ ọlọmọ gbọdọ dide, kẹ şa fẹ ni on to nşe yin, ka gba aya ẹgbẹ ẹni, ka fun ọmọ ẹlomiran loyun melomelo irufẹ iwa ẹgbin bayi, ọpọlọpọ ninu yin kọ loni alarede tirẹ nile ti ko fẹ ki era ko kun to wun, bẹni irufẹ iwa eri wọnyi, a ko le ba won wi awo ko mọ pe on majẹ ata. Bi oko gbe arede gẹgẹ bi ipo ti Ọlọrun fi ẹ si loni, bi oba nhu irufẹ iwa bẹ o dara pupọ, şugbọn ofẹ lọ siwaju nilu, otun nfa ohun eri dani, eyi ko dara to, mo sọ eyi fun itiju ẹnikẹni ti irufẹ iwa bẹ ba wa ni ọwọ rẹ, ọpọlọpọ ti sọ awọn ọmọbinrin pupọ di ero ọrun apapandodo nipa şişi lọna, şugbọn awọn oniwe irohin wa, wọn ki ri irufẹ iyẹn lati ma ke si won leti toto wipe iba on ti Ọlọrun ba şe fun ọ, ni lati tẹ ọ ọrun. Ba ba ni ki ama to bi eto ato aşẹ hunhun şugbọn bi a ko ba sọ bayi ama wun awọn iran to nbọ lẹhin wipe wo awọn lagbaja lẹhin alarede wọn awọn ọmọ won ni Ọba kan, ngbọ iwọ papa kọ ni Ọba kan şugbọn aşẹ oyinbo ti iwọ ntẹ le ha ko ẹ bẹ. Bi oba ma jẹ ọşaka, bo ba ma jẹ oşoko, kojẹ oşoko, aşaka nşoko ko yẹ omo enia laiye. Ẹ jẹki iwa yin ko dara niwaju Ọlọrun, ki ẹri ọkan yin ko si sọ fun yin wipe iwa ododo ni ẹyin nhu, ko ma si si iwa eri ni ọwọ yin mọ.

Mo ri ka ninu iwe irohin Daily News lati ọwọ olotu iwe irohin yi, to si ntọka si wipe ẹnikẹni to ba ma kọ iwe si ẹnikeji rẹ lara, ko fi orukọ ara rẹ sinu rẹ, şugbọn eyi dara bẹ, şe gbogbo enia kọ lo jẹ ọmọluwabi, ọmọ ti wọn bi, ti wọn fi owo wo, awon agbagba lo ma nso loro wipe ko si itiju fun ẹniti oba ti ko aşọ bori bẹni, şe omoluwabi enia lo ma sọ aida si enia lara tan lo si ma fi orukọ ara rẹ si, nigbati ọgbẹni Herbert Macauley C.E. ma kọ iwe nipa ologbe Dokita John Randle ati Ọgbẹni wa Henry Carr I.S.O., ofi oruko rẹ sinu rẹ, şugbon melomelo ni eyiti ọpọlọpọ nkọ ti wọn ko fẹ ki oruko won jade, to jẹ wipe olotu iwe irohin lo ma gba ebu ati isokuso si ori ara rẹ, eyi wa nko, mo niran eyiti o pe ara rẹ ni "Barrister" ninu iwe irohin Daily Times bẹni bo ba fi orukọ ara rẹ si, a gbe jingi ofin gẹgẹbi işẹ on papa aba fi wo ofin wo, ka to mọ eyi ti ama tẹle ka to le sọ irufẹ ẹniti o jẹ şugbọn nigbati o da awọn boju, afi bo mọ lara bẹ, ka to dakẹ, ẹnikẹni to ba fẹ lati pe ija ko fi oruko ara rẹ sode nigbana ni ao fun ni ọwọ to to ati eyi to yẹ fun. Ẹ lo ọgbọn, oye, imọ ati iwe yin si ọna to tọ, ema di ẹru le ẹniti oti şubu mo, nitori ẹyin ti ẹ duro loni le şubu ni ọla.

Igbimọ aşofin asiko nto bọ ti a ni lati yan enia to ja faufau sibẹ enia ti o ma şe otitọ; enia ti o ma şe ododo. enia ti o ma jẹ akọni, enia ti o ma ja

faufau ninu iwe, ninu oye, enia ti o ma sọrọ ọlọgbọn jade, enia ti ọrọ ma da si lẹnu, ki işe enia to ma ma pe gbolohun ọrọ kan ni igba rain to ma jaja sọ ọkan na jade, ki şe enia ti o ma ri awọn ogunna gbongbo ti o nda itọ lẹnu igbin ti şokoto yio ma bọ ni idi rẹ, ki şe enia to ma de ọhun tan to ma ni tinu on ni on ma şe, ki şe enia to ma de ọhun tan, ti a ko ni ri ba sọrọ mọ, ki enia to ma ni nitori oye "Honourable" ni on nşe nlọ, ki şe enia to ma gbe ilu rẹ ta, ki şe enia to ma ni n gbati gbogbo igbimọ fi ohun si ọrọ kan lo jẹ ki on ti on şe ọkan pẹlu won, ki şe enia to ma wipe lotọ ni mo şe fi ọwọ siwe şugbọn eyiti mo ma şe şiku lẹhin, bi nkan ko ba dara loju rẹ to si jẹ ohun to ma mu inira wa fun ilu ni, sọ lẹsẹkẹsẹ wipe emi ko le şe eyi, nitori awọn ti mo je aşoju rẹ' nkan ti ẹ ni ki nşe yi lodi si aşẹ ti wọn fun mi, nwọn ko ni mu ẹ silẹ, nwọn ko ni na ẹ, nwọn ko si ni tori rẹ yọ ẹ ni Igbimọ iyẹn gan loju temi lo ma jẹ ki Ijọba fun ẹ ni ọwọ totọ ati eyi to yẹ wọn a si ri gbangba pe eleyi jẹ olotọ enia nipa bẹ iwọ nşe ododo loju enia ati loju Ọlọrun.

Lọna miran kẹ iwọ ti gbogbo ẹgbẹ ti gbogbo ọgba yan sibẹ, bi o ba wọ ile tan, ekanna ni ko ma fi ja fila lori rẹ, ko ma ni iwọ nki enia, tabi awọn enia ti iwọ ma ma fi oju wo mọlẹ wipe nwọn ko mọ iwe, lotọ nwọn ko mọ iwe şugbọn nwọn mọ ninu ara won, awọn enia bẹ ni wọn duro ti ẹ loni ti wọn si fi ọwo sọ aiya fun ọ wipe iwọ yio de Igbimọ bi wọn Baba rẹ wọn wa mọ iya rẹ bi, awọn mekunnu wọn ni, ni wọn nşe aisun lori rẹ wipe ki Ọlorun ko mu ẹsẹ rẹ wọle, ko si fun ọ ni bujoko rere ni Igbimọ iwọ yio ha tapa si wọn bi? O di ọwọ nyin o!

Ni ijẹrin ni akoja ni Ẹhingbẹti ni arin awọn Ilu ti wọn npe si yara Igbimọ ni *Hall* ti o si ta si wa leti finrin wipe wọn şe aşaro iye awọn ẹniti o ma lọ si Igbimọ lati ọwọ ẹgbẹ Dẹmọ, a si gbọ wipe ninu gbogbo awọn enia patakipataki ti wọn wa nibẹ, pupọ ninu wọn ni awọn ko lọ, wọn si ohun idina rẹ ninu rẹ ni awọn mẹrin kọ iwe si Igbimọ na, nigbati wọn ro si ọtun ro si osi, nwọn si mu Ọlọla Eric. O. More, aşoju ilu kini ni Igbimọ yi, wọn si tun mu Ọlọla Dokita Jones, aşoju ilu keji ni Igbimọ, (ẹniti o gba ọlofẹ lọ si ilu oyinbo ti o si wa ni ọhun, ki Baba ko si mu bọ wa ba wa ni alafia,) wọn si tun mu Lọya Adebayo Doherty, ẹniti o jẹ ọkan ninu aşoju wa ni Igbimọ Munispa —gbogbo ilu yio ri wipe awọn Igbimọ isalẹ wọn gbe jigi nwọn fi wo awọn mẹrin ti wọn kọ iwe wa ẹniti nwọn si mu ni awọn mẹta ti a ka siwaju iwe yi—Gbogbo ilu o wa di işẹ nyin ki ẹ mura ogun lati şe iranlọwọ nyin fun awọn mẹta wọnyi nipa ibo nyin ki wọn le wọ ile gẹgẹ bi ẹ ti şe nigbati Lọya Shyngle (Ologbe ọrun re o) Lọya Moore, Dokita Jones ti nwọn fi wọ ile, ki ẹ tun şe ju bẹ lọ fun awọn ẹni mẹta wọnyi, eyi yio wa han fun nyin gbangba pe awọn Igbimọ isalẹ ẹgbẹ Dẹmọ wọn ni ọgbọn lori wọn ko si şe oju-saju ẹnikẹni, ki wọn to pa imọ pọ mọ awọn ẹni mẹta wọn yi.

Şe ẹnyin na mọ ọrọ ti awọn oni-sọ-ku-sọ ma nsọ wipe Ọgẹni wa Herbert Macaulay lo ma nsọrọ si wọn lẹnu wipe eleyi ni ki ẹ mu, eleyi ni ki ẹ mu, şugbọn loni ko si ni arin wa, ki Ọlọrun mu bọ wa ba wa ni alafia, amin, şugbọn awọn Igbimọ yi ni wọn gbe jigi wo ọrọ na finifini ki wọn to mu awọn ẹniti wọn mu yi, ko ba tun si wahala kan fun wọn ti ko ba si iyọnu ti Dokita Caulcrick, Ọlọrun ko yọ ninnu rẹ si rere, ko ba ti si wahala wọnyi şugbọn ni eyiti awọn ẹgbẹ Igbimọ si pinnu wipe ki wọn mu awọn ẹni mẹta wọnyi, a bẹ nyin gbogbo ilu, ire ilu ni ki gbogbo nyin fi si ero, ẹ ma wo wipe lagbaja kere tabi o dagba şugbọn ohun ti o wa fun wa ni lati duro ti eyiti o kere lati ma ke tantan fun eyiti o dagba ki wọn le mọ ọkọ wọn lati tọ—Ki awọn ẹgbẹ "Young Nigerian, Civil Servants, Railway Union" ati gbogbo awọn ẹgbẹ yoku ki wọn dide bi ti akọko ki wọn şe iranlọwọ ki awọn ẹni wa wọnyi le wọle, Ọlọrun ko ni jẹ ki oju ki o ti nyin.

Nitori na ni ipade ti ọsẹ yi, ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ gba wọ jọ, ki wọn fi ohun şe ọkan lori ẹni mẹta wọnyi, nitori ajọ wo, ohun ti a ba jọ wo ni-gun Asiko wa fun ọpọlọpọ elomiran lati lọ si Igbimọ suru lo gba, bi nkan ko ba ti to asiko rẹ ki oluwarẹ ma ti kanju gbogbo nkan nlọ fun rere ni oju Oluwa. Işẹ ti o ti nşe fun ẹgbẹ ma lori bi sẹhin, ma şe gẹgẹ bi Ọlọrun ba ti fi ran ẹ, lagbaja lo nşe mi, mu iyẹn kuro lẹnu, tamẹdu ni ko jẹ ki ẹgbẹ yan mi, aroye ọtẹ ni, Ọlọrun ni ko ti fẹ ki nkan yi şe ni, duro ti awọn ẹni mẹta yi giri-giri, Oluwa yio ran nyin lọwọ.

Ki nto pari ọrọ mi, mo fẹ lati fi han ẹyin ti wa ni ẹhin agbo wipe kẹ bọ si gbangba kẹ ma bọ, nitori Herbert Macauley ni ko jẹ ki nrin ọgbọn mi wa, bi aba ba sọrọ ki gba ti inu rẹ lo ma ma şe, nitorina aye wa fun gbogbo yin kẹ ma bọ, nitori Kiniwun Onibudo ko si ni ile, aye wa fun ẹnikẹni kẹ ma bọ, ki ẹ wa wo ohun ti Dẹmọ nşe bi buruku ni tabi rere bi o ndi ọtẹ si Ijọba ni tabi o nta ijọba lọya nigbana ni ẹ le sọ ni gasi kia ohun to ru yin ninu, nigbana ni ẹ o le jihin fun Ọba na wipe otọ ni Dẹmọ nşe—Abọ mi re o.

Emi ni ti nyin nitotọ,

ENIA KO DA BI ALLAH

---

## AGBAKO ORI EDE.

A gbọ wipe motọ pa ẹnikan ni Oshodi ni ọsan Wednesday ọsẹ yi, a gbọ pe nigbati ewu na şẹlẹ tan awamotọ fẹ jalugbo, a ko mọ iru ohun ti o mu asişe na wa. Lọwọ agbako buburu Oluwa rere gba wa.

## ORI IV.

## IŞẸ.

*(Translated from "Character by Dr. Smiles").*

APA KẸRINLA.

Helvetius tilẹ fi oke le po, mimọ ti enia mọ pe ohun kan wa ti a npe ni airikanşekan ni a fi ju ẹranko lọ—pe nitoriti o mọ pe ẹranyan ni ki a gba ara wa lọwọ ko ba ara de iya ti airikanşe imu ni jẹ ni imu enia wa ọkan şe, nitorina si ni o fi jẹ eyi ti imu enia lọ siwaju.

Ni gasikia, iwa işẹ şişe nigbakugba ti a sọ yi, ti ọpọlọpọ işẹ, ti biba awọn ti o nşe aiye lo, lati aiye-baiye ni eyi jẹ ohun ti imu iwa işẹ şişe awọn ẹniti o ni iwa gbo.

Ekọ işẹ şişe wulo bakana lọna işẹ-kişẹ—bi lọna işẹ ilu-şişe ni, bi lọna ti işẹ iwe ni biti ọna iwadi Ọgbọn ijinlẹ ni, tabi lọna işẹ Ọna.

Nitorina ni a ri i pe ninu işẹ iwe-şişe eyiti o pọ ju ni eyiti awọn ti o kọ ọna işẹ şişe kọ.

Lala, ifarada, aigbe akoko sọnu ati a jẹ alagbara ma mọ ero awọn iwa ti o mu wọn wulo lọna işẹ kan si tun wulo işẹ miran.

Ọgọrọ awọn okọwe atijọ ti ilu Gẹsi ni o jẹ awọn ẹniti o ti kọ işẹ; ko sa ti işi awọn kan ti a mọ yatọ ni gbana ni Oniwe, afi bi awon Alufa. Chaucer baba awọn ti o kọ iwe arofọ-orin ti Gẹsi kọkọ şe agbebọn, lẹhin na ni o wa şişe ni ibode. Ki işe pe o nfi ọwọ pa işẹ o si ngba owo lasan ni; on papa ni o ni lati ko gbogbo iwe işẹ na; lẹhin ti o ba ti şe gbogbo işẹ rẹ ni ibode, a fi tayọ tayọ lọ si ile lọ ba awọn iwe ti o nkọ a kunri mọ titi oju rẹ a şokun ti a fẹrẹ ma riran mọ.

Awọn Okọwe pataki ni aye Ọba Elizabeth, nigbati ẹkọ iwa rere awọn ara ilu England bẹrẹ si gbilẹ si, ki işe awọn ti a le pe ni omọwe ni aiye isisiyi, şugbọn nwọn jẹ awọn ẹniti a ti fi ọna işẹ şişe kọ. Spenser şe işẹ akọwe (Secretary) fun Lord Deputy of Ireland; Raleigh şe ọmọ lẹhin oloye, o şe agbebọn, o şişẹ ninu ọkọ, o si wa şişẹ wiwa ilu titun kan.

Sidnay şişe ilu, o şişẹ Ọba o si tun şe agbebọn: Ki Bacon to di Lord Keeper ati Lord Chancellor o ti kọkọ fi gbogbo ara şe işẹ lawyer; Sir Thomas Browne ti kọ şe işẹ Onişegun ni ilu oke ni Norwich: Hooker ti kọ şe wabiwọsi ninu işe alufa ijọ kan ni ilu oke; Shakespeare şe Olotu ileere (theatre) şugbọn on papa ko kọra si ere şişe ni lari, o tilẹ dabi ẹnipe ti ere ti o ma ri jẹ ni o wa lori ẹmi rẹ ju ti pipe işẹ na ni nkan danyin-danyin.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

---

## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oşupa mi" jẹ ojulowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le şẹşẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Şango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Orişi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Şabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maşe gbẹhin ki ẹ to ranşẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, SEPTEMBER 15, 1928.

## AGBOMIRAJIGI ORUKỌ ẸGBẸ DẸMỌ.

Ko si botiri ni Ipade Ẹgbẹ Dẹmọ ti a ṣe ni Ile Afariogun l'Ẹhingbẹti ni ọjọrọ Satide ti o kọja nigbati gbogbo ẹsẹ awọn ọmọ Ẹgbẹ pe perepere sibẹ: Ọgbẹni Ọlọla Eric O. Moore ti o joko sori aga sọrọ itunu pupọ fun Ẹgbẹ fun idanwo nlanla ti Ẹgbẹ na la rekọja nilọlọyi nipasẹ ti ọrọ Ọgbẹni Herbert Macaulay pẹ si ni a gbọ pe awọn jakanjakan miran tun sọro iṣiri pẹlu ohun pataki ti Ẹgbẹ muṣe ni iṣe ni ti pipalẹmọ ati yan enia mẹta sinu Ajọ Igbimọ Aṣofin *Nigeria* nipa didibo fun nwọn: gẹgẹbi a ti sọ ni ọsẹ ti o kọja, pupọ awọn ẹlomiran ni yio ma lakaka lati ko enia so'di pe ki nwọn ba le dibo fun wọn nitoripe ero inu awọn ti a nwi yi dabi owe kan ti o sọpe "ologbo r'ajo ile di ile ekute" ṣugbọn a mọ pe ẹhin igba ni irufẹ awọn ẹnibẹ nyin igbado si, nitoripe awọn ti nwọn wa ni idi ina ko ni jẹ ki o ku. "Aja l'ọlẹru, irọ ni pẹpẹ npa" kosi inu ẹniti ko dun si imura ti Ẹgbẹ Dẹmọ mura nisisiyi lati maṣe fun ẹnikẹni laye lati di wọn lọwọ fun iṣẹ ribiribi yiyan enia yi, nitotọ a ko sọ pe ki awọn ẹlomiran maṣẹ ṣe fitafita diẹ lọna tiwọn a ko si ni ki irufẹ awọn wọnyi maṣe fi poun mẹwa wọn gbagi ija ko sa si ninu Ogundareke ṣugbọn ohun ti a ntẹnu mọ gidigidi nipe gẹgẹbi Dẹmọ ti jẹ Ẹgbẹ Ilu, ti o si jẹ pe Ẹgbẹ yi nikan ni o wa gẹgẹbi Ẹgbẹ ti ma wa ati jubẹlọ gẹgẹbi o si ti jẹ pe irufẹ iṣe didibo fun awọn ẹniti Ilu yio yan lọ si *Council* ni a ṣe da Ẹgbẹ na silẹ o yẹ gidigidi pe awọn ẹniti Dẹmọ ba dibo fun loyẹ ki nwọn bọ si ipo yi ni Ajọ Igbimọ na; a tanma pe ki yio si ninu awọn ọmọ Ẹgbẹ yi ti nwọn to dibo ti yio gbẹhin b'ẹbọ jẹ nigbati asiko ba to.

Laisi ani ani Ilu ti ri iṣẹ ribiribi ti awọn mẹta ti a ti yan sibẹ ti nṣe bọ lati ọdun marun yi wa ninu iṣẹ na ni Ọgbẹni Ọlọla J. Egerton Shyngle ṣalaisi, ti Dokita J. A. Caulcrick si rọpo rẹ ẹnyin ko ṣai ri iṣẹ ti Olukuluku awọn ẹniti Ilu yan yi ti nṣe bọ lati ẹhin wa.

Ọdun 1928 jẹ ọdun idanwo lọpọlọpọ fun Dẹmọ, ṣugbọn sibẹsibẹ koyẹ ki idamu ka Ẹgbẹ nitori gbogbo nkan wọnyi tani ko mọ pe iyọ ati iṣa lo mbẹ laiye. Bawo ni ọdun karun ijelo ko ti dundun to nigbati ọjọ didibo akọkọ ya? Ire si jẹ ki Ilu mura giri ni didibo ekeji yi ki irẹwẹsi maṣe ri ẹnikẹni ninu ọmọ Ẹgbẹ gbe ṣe.

Ẹ fi awọn ti nwọn nṣata ti nwọn si fi ẹrẹkẹ ebu ṣe ọja tita ninu iwe-irohin wọn silẹ, awọn ti o jẹ pe ara ki rọ ayaṣebi nwọn ba tọ ẹniti ko to wọn: nje ninu awọn ti nwọn nṣata Ọgbẹni Macaulay wọnyi a ko ma ri ninu wọn ti nwọn ti ṣe "majẹ-agbọ" kan ri? Ṣiọ, tani ina pẹhinda ti ko ni ọrọ "Ṣugbọn" lara!

Iṣẹ ti Dẹmọ nṣe nisisiyi ju riraye lati ma da a wọn Bunibuni Abebu wọ-ntiti wọ-ntiti lohun lọ.

Iṣiri ti ipade Dẹmọ ọsẹ tokọja mu wa fun ilu daradara lọpọlọpọ: a mọ pe bo ṣe ajin oru ni a pe Ipade yi, bakanna ni ile Ẹgbẹ yio kun de ẹnu: Ẹ gbọ melo ni awọn ẹlomiran le pe, pe ki ile ki o kun ki ọna sibo eyiyi fihan ni pe Ẹgbẹ Dẹmọ ti di ọkanṣọṣọ arada ti o to ẹgba ọṣunsun.

Lẹkansi, a kesi ẹyin alakoso Ẹgbẹ lati mira jigi fun iṣẹ ribiribi didibo yi, ki ẹ ma si jẹ ki ọpọlọ kan ri aye sẹ'gi si nyin lara nipa biba nyin du didibo yi.

A di gari silẹ
Ọmọ ewurẹ nroju
Ẹru baba rẹ ni bi o?
Agbẹdọ! Agbẹ'ẹdọ!!
Agbẹdọ gbẹdọ!!!

---

## Ẹ KU RỌJU.

A ba Mrs. J. O. Thomas ti 47 Smith Street Eko kẹdun iku ẹgbọn rẹ Mr. H. O. Williams ti o ṣẹlẹ ni Ebute Mẹta ninu ọsẹ yi.

Ki Baba gbe s'afẹfẹ rere.

## Olusakin's Column.

### The Arrival of His Excellency The Goveanor and Lady Thomson.

Their Excellencies the Governor and Lady Thomson and the Governor's personal staff arrived Lagos on Monday the 10th September, 1928, from the tour of Inspection.

### The Legislative Council Election.

According to *Nigeria Gazette* of the 30th August last, the Polling day for the election of three Lagos Members to the Legislative Council has been fixed for Friday, the 28th September, 1928, at the Glover Memorial Hall at 8 a.m.

### The Retirement of Dr. K. Faderin.

It is stated on good authority that Dr. Kubolajẹ Faderin, M.B., ch.B., Medical Officer, Ebute Metta Dispensary, will retire on pension after the expiration of his present vacation leave.

Dr. Faderin joined Service on the 14th July, 1914, and rendered a valuable and meritorious services.

We wish Dr. Faderin and his amiable wife long life of future happiness and usefulness, and in whatever sphere of life the future finds them.

### On Leave.

Mr. Joseph O. Oshoba, 2nd Class Compositor, Railway Press, Ebute Metta, who has been on a month's leave, as from the 12th September, 1928. Mr. Oshoba hopes to visit Kano to spend some portion of his leave.

### Promotion.

Mr. Moses O. Denloye, 1st class Clerk, Nigerian Railway Accounts Department, Ebute Metta, has been promoted to the rank of an Assistant Chief Clerk, as from the 1st April, 1928.

Congratulation.

OLUŞAKIN.

## ỌRỌ OLOYE OLUWA NI AJỌ DẸMỌ NI SATIDE TOKỌJA.

Inu mi dun lati ri yin nibi losan yi: a da Ẹgbẹ Dẹmọ silẹ fun rere ilu yi ati awọn enia inu rẹ: o jẹ fun rere awọn ọmọ Ẹgbẹ ati awọn ti nwọn npe ara wọn ni ọta Ẹgbẹ na. O jẹ rere Ijọba pẹlu.

Mo sọpe ojẹ fun rere Ijọba nitoripe awọn Gẹsi ni irufẹ Ẹgbẹ bayi ni ilu wọn Ẹgbẹ ti o nja fun rere ilu wọn: ko si si ẹnikẹni ti o ma pe irufẹ Ẹgbẹ bayi ọta Ijọba. Ni ilu Eko kosi Oyinbo kan ti o jẹ ọta Eko: gbogbo wọn lo fẹran wa: diẹ ninu awa Enia dudu ni nwọ nlọ gbọ yi sọ yi fun wọn tobẹ ti inu fi nbi won si wa: ṣugbọn adura wa ni pe kị Ọlọrun le yi irufẹ awọn Enia dudu bẹ lọkan pada.

Awa dupẹ pe Ọgbẹni Herbert Macaulay koi ti ku o nsimi fun igba diẹ ni, nitorina ẹyin ti ẹ nsọpe "mba ṣe nkan bayi-bayi fun Ẹgbẹ, mo ni imọran rere kan fun Ẹgbẹ, Macaulay nikan ni ki fun ni aye" okan nyin wayi lati wa da bira ti yin: awọn ti mo nba sọ eyi ni ẹnyin Kiriyo onişokoto gbọrọ: awa Oloye ati agbada ko mọ edemeji awa ko le lọ si Ajọ Igbimọ Aşofin ti Ọba ki o jẹ pe awa na mọwe bi ẹnyin ni, ko ni si ẹni tole fọwọ rọ wa sẹhin ni ọjọ idibo ẹ ba gba ọye Oyinb lati A. B. C. de Z, ẹ ba le di Kọla de eti ẹ ko le lewa sile ni ọjọ didibo o da wa loju pe Fila fun kekeke ori wa yi ni a o fi yi nyin mọlẹ kitikiti: şugbọn a ko mọ iwe a ko le sọ ede Oyinbo ti o jẹ ede ewọn Olotu wa. Ẹnyin ni a ni lati yan si Ajọ Igbimọ, pupọ ninu si jẹ Atohun-rinwa, şugbọn ti ẹnikan ninu nyin ba da wa Ọlọrun l'le yi yio bi lere.

*From Lagos Daily News of 10/9/28.*

## IPADE DẸMỌ.

### Lati ọwọ Kekere-Awo.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete.*

Mo bẹrẹ f'oji,

Ni ọjọ Satide tokọja ọjọ kẹjọ oşu yi, ni awọn ẹgbẹ "Democratic Party" şe ipade Gbogbo-gbo jabẹ Alaga Ọlọla Lọya Eric O. Moore ati awọn Ojoye Onifila-funfun, Eletu Odibo Oloye Oluwa, Oloye Ọlọtọ, Ashogbọn ati Oloye Oshodi Saka, ati awọn Ọgbẹni Thomas, H. Jackson, Councillor J. Bagan Benjamin, C.F., Lọya T. A. Doherty, Lemọmu Amọdẹ, Lemọmu Alafayat, Lemọmu Lawani Aguda, Alaji Abudu Salami Davies, Alfa Bello Arọwasi ati awọn Lemọmu Ratibi miran ati awọn jakanjakan ni gbajumọ Kiroyo ati Imale pẹlu ti a ko le ri aye lati ma daruko wọn lọ titi.

Şibaşiba ni ẹsẹ gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ pe, nwọn fẹrẹ to ẹgbẹrun mẹrin ti nwọn wa si ipade na

Oye ti a ri ni ipade na ni wipe nwọn ko tete fun awọn ẹniti ko ni ami-ẹgbẹ tabi ti ko mu ami-ẹgbẹ dani ni aye lati wọ ile, nwọn si ngba owo ọdọdun ti nwọn ma nda lọwọ awọn Omọ-ẹgbẹ ti o jẹ ẹgbẹ ni igbese gẹgẹbi nwọn ti fi sinu iwe-akiyesi ti nwọn fi kede ipade ẹgbẹ.

Ki nwọn to bẹrẹsi ọrọ Ajọ ni nwọn ngba owo lọwọ awọn ẹniti o jẹ ẹgbẹ ni gbese, nwọn si nṣe Risiti owo ti olukuluku wọn san le wọn lọwọ, owo ti nwọn ri gba lọjọ na to pọnun mejidinlọgbọn o le şile mẹrin ati kọbọ meji, lẹhin eyi ni awọn ẹniti nwọn ngba owo yi sọ wipe ẹgbẹ nfẹ to ọgbọn pọnun gere.

Nwọn sọ wipe inawo ti ẹgbẹ yi nşe si ibiti awọn npe si yi ki işe inawo kekere arara, lẹhin ti awọn ba san pọnun mẹjọ owo ile-ẹgbẹ, awọn si tun nsan owo omiran bi owo aga ti ẹgbẹ nlo, nwọn ni gbogbo re ẹna ẹgbẹ nigbati awọn ba nşe ipade bayi nigba miran o to pọnun bi mẹrin-din-logun, nitorina ki olukuluku ma gbiyanju daradara, nwọn si şe adura fun awọn ẹniti o nda owo diẹ-diẹ, ki Ọlọrun si ma fun awọn ẹniti ko nri ọwọ yọ gbe ni aye ti anfani.

Ajọ bẹrẹ ni iwọn agogo marun kọja işẹju mẹwa.

Ọlọla Lọya Moore :—Mo ki gbogbo nyin pupọ mo ro wipe o to ọjọ mẹta tabi lati ọjọ kẹrinla oşu *January* ti ẹgbẹ yi tişe ajọ, nri ti mo si ri nyin nhin loni, bakanna li ẹ wa loju mi, eyi mu ki inu mi gidigidi.

Nkan pataki kan li a şe ipade fun nihin loni, ki nto bẹrẹsi ọrọ mi, ngo sọ ohun ti a şe ni Ajọ ti Kọmiti ti a şe l ọjọ Alamisi ọjọ kẹfa oşu yi fun nyin. A kẹdun ti ọm'Ọba David Omoyẹle Dosunmu ti o şe alaisi ni Ikọyi, a kẹdun ti ọfọ Daddy John Amblestone ẹniti o ku ni ile rẹ ni Ebute Mẹta lọjọ *Tuesday* ọjọ kẹrin oşu yi. Pataki kan ninu ẹgbẹ yi ni Daddy na nşe, ki isi siba pa ẹgbẹ jẹ nigbagbogbo, Daddy na lo nfi ẹrọ la igi ni Ebule ẹlẹtun.

Lẹhinna a tun şe ikẹdun fun nyin nipa ajalu ti o ba Ọgbẹni wa Herber Macaulay, C. E ati Dokita Caulcrick M B fun ọjọ ti nwọn ba wọn şe ni lọlọyi, a kọ fẹ ki gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ fi ọkan si sibẹ daindain ki a maşe banujẹ, ki a fi ọkan si wipe ohun Ọlọrun fẹ ni şugbọn ki a mọ wipe Ọlọrun Ọba ki işe ibi, ki gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ şa şe giri, ninu ajọ ti a şe ni Kọmiti a şe şawura nipa iwe ikede ti awọn Ijọba fi si ode lati yan awọn ẹniti titun mẹta ti yio şe Oju wa ni Igbimọ, gẹgẹbi o ti jẹ wipe ni ogunjọ oşu yi ti o ku ọjọ mẹwa ni akoko awọn ẹniti o ti wa ni Kansulu na ri yio pe, ti o ba si di ni ọjọ mejidin logun oşu yi ni a ni lati fi awọn mẹta titun miran sibẹ. A si ti sọ ni Kọmiti wipe awọn ẹniti o ba nfẹ lọ ki nwọn kọ iwe wa fun awọn titi ọjọ Atalata to mbọ eyiyi ni ọjọ kọkanla oşu yi (tabi ni Atalata ijarun) ninu gbogbo ẹniti o ba kọ iwe wa lati lọ şe Kansulu, li awọn yio mu awọn mẹta ti ẹgbẹ ba fẹ.

Awọn yio si fi iwe kan si ode nipa eyi, nitori awọn ni lati jẹki gbogbo ẹgbẹ mọ awọn ẹni mẹta ti ẹgbẹ mu lati dibo fun.

Ohun ti mo fẹ ki a mọ ni wipe aseko na de tan ko ju ọjọ mọkan-le-logun lọ, ki a ma si şe dẹyidẹyi kan si arara, nitori bi awọn ti ngbaradi lọwọ yi, bẹni awọn ọta papa yio ma mura tiwọn nisisiyi, nitori awọn ko mọ irufẹ ara ti nwọn nnu lọwọ, ki a gbiyanju daradara, ki a duro gbọnyin. OLOYE OLUWA :—Mo dupẹ lọwọ Aliga fun iyanju ti o gba wa, inu mi dun lati ri nyin nihin loni.

Nwọn da ẹgbẹ yi sile fun rere ilu yi ati fun ire gbogbo awọn Omọ-ẹgbẹ yi, ẹgbẹ yi mbẹ fun ire ọkunrin, obinrin, ọmọde ati fun agbalagba fun ire dudu ati fun ire funfun pẹlu, ati fun ire gbogbo awọn ẹniti o mu ẹgbẹ yi ni ọta.

Mo ni fun ire awọn funfun nitoripe awọn funfun nja fun ilu wọn, nwọn ko si sọ wipe awọn nyẹn ọta Ij ba ni nwọn nşe, a ko da ẹgbe yi silẹ fun işikan arara, nitorina ki eyi maşe jẹ kọdọyi fun nyin nipa awọn funfun ti a darukọ pẹlu.

Ninu ilu yi kosi funfun kan yala ninu Ijọba tabi omiran ti o jẹ ọta ilu nwọn fẹran wa, ara awa Enia Dudu li a nlo ba wọn ti a nsọrọ aidara si arawa lọdọ wọn, şugbọn a mbẹ Ọlọrun ki o rọ iru awọn enia bẹ lọkan, orin ti nwọn nkọ ni Ọyọ li a gbọ, a ko gbọ ilu ti nwọn nlu ọhun Owe ni o.

A dupẹ lọwọ Ọlọrun nisisiyi wipe Ọgbẹni Makọli koi ku, o yẹra kuro larin wa ni, bi ẹnikan ba mbi ẹnikan lere pe kini oro ilu yi ti nlọ si, ekeji yio dahun pe Makọli ni ko jẹ ki on le mọ ohun kan lati şe, bi awọn tilẹ fẹ lati ma nawo, tabi lati ma fi ara şe, Makọli ko gba awọn laye arara lati le şe ohun ti awọn le şe, wayi o o kan nyin, Ọgbẹni Macaulay kosi larin wa nisisiyi, gbangbadẹkun kedere bẹwo, gbogbo ẹnyin ti ẹ ti nleri leki aye şi silẹ fun nyin wayi.

Ẹ jade ẹ wa sa agbara nyin, ẹnyin ti ẹ mọ iwe li a mba wi.

Aparo o dide ni ọjọ kan o pe aya rẹ, o ni njẹ bi on ba ku njẹ o ki yio ni ọkọ miran? aya aparo wo titi, o ni dara o ko sinu eru, o ni njẹ iwọ yẹ ka'wo, iwọ yẹ ka'wo, Owe ni, gbogbo Ọmọ ẹgbẹ ho ge.........e !

Makọli lo da ẹgbe yi silẹ şugbọn ko da sile fun ire ararẹ bikoşe fun ilu rẹ, nipa ibo ti awọn nsọrọ rẹ yi, Makọli ko fi igba kan sọ wipe on nlọ si Igbimọ, bẹni awọn Ọjọye ti awọn nsọrọ yi, awọn ko fi igba kan sọ wipe awọn nlọ si Igbimọ, bẹni awọn Lemọmu ko sọ wipe nwọn nlọ si Kansulu, ẹnyin elede meji ti ẹ gbọ ohun ti awọn nsọ nihin ti ẹ si gbọ ede ti nwọn nsọ lọhun li awọn mba wi, ani ẹnyin ti ẹ mọwe daradara, ẹnyin Oni Şokoto gbọrọ ti Kọla nyin ga daradara li awọn mba wi,

nitori awọn kọ mọ iwe tabi ti awọn yio fọ ede, ṣugbọn Fila ori awọn yi ati aṣọ olowoyọ funfun ti awọn da bora, a le fi yangan le ẹnyin lori, ẹnyin ni awọn ni lati ran lọ si Igbimọ, ti awọn ba si ran nyin lọ si Igbimọ na, eyiti o ba de ibẹ tan ti o ba wa sọ wipe wayi, on de ibẹ tan, yio ma wa mu ti ara on ṣe, Ọlọrun ti o ni ilẹ yi yio da a fun oluwarẹ.

Ẹnikẹni ninu awọn enia Enia Dudu ti o ba si sọ wipe on yio ba ilẹ yi jẹ, ilẹ yi yio bi oluwarẹ lere.

Ẹ ko gbọ bi Owe kan ti wi Owe na sọ wipe :—alọ iṣu sile Ẹlẹgbara, abọ itọ sile Oriṣa-nla, idaripadaabọ itẹnabọ Mọṣalaṣi, bi Ẹlẹgbara ko bere tirẹ, bi Oriṣa-nla ko bere tirẹ, bi Imale ko bere tirẹ, Ọlọrun Ọba to ni Mọṣalaṣi ko ni bere ; nitorina o dọwọ nyin.

ALAGA :—Ẹniti o ba ni ọrọ lati sọ lara Ọmọẹgbẹ lọkunrin tabi lobinrin, awọn fi aye silẹ ki o ma dabi ẹnipe ṣe mo tilẹ fẹ sọrọ, ṣugbọn nwọn ko jẹki on ri aye sọrọ.

Ọkunrin kan dide, o ni on ki gbogbo Ọmọ-ẹgbẹ patapata, inu on dun lati ri nyin losan yi, on ko tilẹ ni ero pe on yio wa si ẹgbẹ loni, iṣẹ mọto ti on nṣe, on ki ipa ẹgbẹ jẹ, ṣugbọn nigbakugba ti ẹgbẹ ba nfẹ ni Ọlọrun ma nfun on ni aye ti on si wa.

Ohun ti o mu on sọ wipe on ko ni ero pe on yio le wa si ipade oni yi ni wipe nigbati, on gbọ ti ajalu ti o ba Ọgbẹni Makọli o ba on ninu jẹ patapata, ṣugbọn ki Ọlọrun ma jẹki awọn ri ohun ti yio ba wọn ninu jẹ—Amin.

Ẹnikan tun sọrọ, o ni ninu ẹgbẹ Ọmọ-ogun Igbala li on wa, on si tun jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ yi, o kẹdun nipa ti Ọgbẹni Makọli gẹgẹbi o ti jẹ wipe nigbati awọn gbọ, ẹru ba awọn, ẹniti o njẹun lọjọ na kole jẹ ẹ mọ.

Ẹnikan tun dide, o ni ọkan ninu Ẹtiopia ni on, on si ti de ilẹ yi lati ọmọ ọdun mẹfa ṣaṣa enia ni ko mọ on, koda Alaga yi papa mọ on, o ni rere ilu yi li on nfẹ, nitori on ni obinrin sibẹ on bimọ sibẹ sibẹ on nṣiṣẹ on jẹun nibẹ, on nsun on nji nibẹ, on ko mọ ọna ti on ki yio gba, ti on ki yio fi ma wa rere ilẹ yi, o sọrọ pupọ.

Lẹhinna ni obinrin Jariọgbe Oniwaka wa dide o sọrọ, o ki gbogbo ọmọ-ẹgbẹ patapata, o si gba wọn ni iyanju wipe ki nwọn duro girigiri, obinrin ni awọn, kosi ohun ti awọn le ṣe, ṣugbọn bi awọn ba ti nri ẹnyin ọkunrin ọkan awọn yio ma balẹ daradara, awọn kosi fẹ ki ẹ da awọn nitori awọn ki yio da nyin, ṣugbọn ti ẹ ba da awọn ẹnyin ni iyẹn Ọlọrun ni iyẹn.

Ọlọla Moore:—On dupẹ lọwọ gbogbo awọn ẹniti o sọrọ, bi awọn ba tiṣe si ni Kọmiti awọn yio jẹki ọmọ-ẹgbẹ gbọ awọn si ro wipe ajọ omiran yio wa ni Satide ti mbọ, awọn le fi iwe si ode, awọn si le ṣe alai fi iwe si ode.

Ajọ tuka ni dede agogo meje ku iṣẹju mẹwa, ajọ o tu o ! Ipade Dẹmọ tun mbẹ loni.

Emi ni ti nyin nitotọ,
KEKERE-AWO.

---

## ILE-IFE.

Mo dupẹ lọwọ awọn aṣaju wa gbogbo o. Mo si juba ẹsẹ ati iba atẹlẹsẹ ti ko wurun ti ofi dojugun.

Mo dupẹ lọwọ ẹniti ori, ti ọgbọ ti osi ko irohin Ile-Ifẹ ti o wa ninu Iwe Irohin Eko Akete ti August 4. Inu mi dun lati sọ fen gbogbo awọn enia pe Olowemowe nipa ti Ile ati ti ọmọ onile ni popo Irẹmọ.

Lotọ ni gbogbo ọrọ ti Oniwe irohin *Eko Akete* na sọ nipa wipe ọmọ onilẹ ntẹ jẹjẹ ati ajoji ntẹ girigiri ni Ile-Ifẹ nisisiyi, ki ohun gbogbo le ba dara na ni. Nko ni bu kuro ninu ohun tinwọn ti kọ silẹ ṣugbọn mo bẹbẹ lati ladi diẹ ati lati fi kun awọn ọrọ wọnyi.

Lotọ a ki ṣe fun ọyọ ni ọdẹdẹ to ba ṣe diẹ a gbo kankan le, ki o ma ṣe bi owe o, Ọyọ ti ẹwi yi nitotọ on lọ kọ ile yi ṣugbọn fun igba diẹ ni ọni lati gbe ninu rẹ, eyini nipe titi owọ ihaya rẹ yio fi pe, oye ti ọna lati fi mo ogiri ati ti panu rẹ (The land whereon he built is leased to him for a limited period) nitori bi aba bi Ọyọ yi lere wipe ẹlomi o ra ilẹ ti okọ ile le lori dajudaju ko le ri oye kan darukọ wipe oye pound bayi ni, ko si tun le wipe oye bàyi ni mo nsan fun onile ni oṣoṣu nitori owo ti iba ma san nlọ si apo ara rẹ fun inawo ogiri ati ti panu ile na i.e. The corrugated iron and walling expenditure. Awọn onile yi ko jẹ fi ilẹ tabi ile fun Ọyọ yi patapata nitori (1) Ki nwọn ma ba jẹbi awọn ọmọ won lẹhin ọla ati ki nwọn ma ba gba epe awọn iran ti nbọ sori pẹlu.

2. Nitoripe awọn ọmọ onile yi mbọ lati wa lo ile na fun ara wọn nipa ifẹ Ọlọrun, a si ri pe awọn eyo wẹwẹ po ni arin ile ki Oluwa ki oda wọn si o. Atipe ọmọ inu ile yi kan jẹ akẹkọ ni Ile Iwe giga ni Ọyọ i.e.

A student of St. Andrew's College Ọyọ ẹniti o duro fun Ifẹ ni ipo rẹ i.e., an Ifẹ representative in his class and he is likely to be a schoolmaster In one of these days D.V., nitorina a ko le ro eleyi pin ki asi fi wipe a mọ iwe rẹjẹ tabi ki afi igboju gba ile rẹ.

3. Awọn Ọyọ ti danna si awọn onile yi loju ni oko wọn eyini ni wipe awọn Ọyọ ti baba onile yi gba si oko lati ma ro ilẹ ati lati ma jẹun nibẹ yọ ọ lẹnu lọpọlọpọ fun igba diẹ ti nwọn si le kuro rẹ bọ si Ile fun iwọn ọdun meje nitoripe nwọn wipe oko ti won ni, ọpẹlọpẹ onilẹ ti o otun lẹ ṣe ti ko si fẹ fi idi onile le alejo lọwọ ni ojẹ ki onile yi ri idi mulẹ diẹ kinnn ni oko na, nitorina mo sọ

bayi pe ki ẹmi Ọba ki ogun ki osi le ma jọba awọn enia rẹ ni alafia. Fun idi eyi onile yi ko le fi kiun ninu ile rẹ ṣe sara fun Ọyọ kan rara nitoripe ija tabi iyọnu Ọyọ ko dara, dajudaju bi aba pe onile yi lati sọ diẹ nipa iyọnu (trouble) Ọyọ yio ri ro o.

Nitorina ki ẹnyin agba Ifẹ, alabojuto, ati awọn aṣelu fa ara mọra ki iwosi ma ba ma ko si yin labẹ. Nitoripe owe tabi afiṣọrọ Ọba wa sọ bayi pe "Ipapọṣọkan jẹ agbara" i.e. His Highness the Ọni of Ifẹ's motto is "Unity is strength". Nitorina ki ilu to ni agbara nwọn ni lati wa ni ọkan kan ati Idapọṣọkan.

ỌMỌ YESIRENI.

---

## Enugu News.

### !IRE A KA RI!

Chief Sanni Animashaun ṣe ọjọbi fun ọmọ rẹ kekere ti o njẹ Abassi Kehinde ẹniti o di ọdun meji pẹlu oṣu kan ni ọjọ Friday 31st August, 1928. O se ase onjẹ rẹpẹtẹ pẹlu nkan mimu fun awọn Alagba ti o pe ni ọjọ na.

Eyi yi ni orukọ awọn Alagba na :—

Inspector Sanyaolu Eqs.<br>
Mr. Olukolu<br>
„ Mọmọdu Smith<br>
„ E. H. Badaru<br>
„ Adekiti Demosu

A ki ẹyin Alagba—Ẹ ku idide. Bẹ akari o Amin.

---

### IJẸKUJẸ TI PA APARANBI.

Ni irọlẹ ọjọ *Sunday* ọsẹ tokọja 9-9-28, nigbati a nkọja lọ ni opopo Reclamation Road, ni a ri Ọgbẹni Awusa kan ti o sun silẹ bi eyi to ku ki awọn ọmọde to pe bo, nigbati a bere idi ohun to mu Ọgbẹni yi ki o to sun bayi ni awọn ẹgbẹ rẹ wa sọ fun wa pe atẹnujẹ lo npa Ọgbẹni na lo bayi eyi ti nwọn npe ni ọti.

### AIMỌ IWỌN ARA ẸNI L'ỌMỌDE FI NFOJU DI NI.

Ari awọn ọmọde ti nwọn ko ara wọn jọ tẹle ọkunrin kan pẹlu oko lọwọ, ti awọn ọmọde na bẹrẹ si sọ oko lu Ọgbẹni na, ki ti gbe o, ọlọmọ wẹwẹ ẹ kilọ fun ọmọ nyin o, ki wọn ma ba ko ẹhin ṣe libi ṣe lọhun wa ba ẹnyin obi ọn o.

w

### ITIJU WỌ NI L'ỌRUN JU ẸRU LỌ.

Ni Satide ijẹjọ ni a ri ọdọmọkunrin kan ni apa Oke-popo pẹlu pẹpẹiyẹ meji eyi ti o so mọ ọrun ati panpẹ tabi ṣẹkẹṣẹkẹ lọwọ mejeji ti awọn ọlọpa ilu nfi ọwọ ti l'ọrun ti nwọn ba burin burin nwọn a fi meji ki wọn gboran ba eyi to nmu fọ ohun aro pe o pari wayi o pẹpẹiyẹ kẹ, ọjọ gbogbo ni ti ole, ọjọ kan ni ti olohun.

### AGBALAGBA NJẸ IKA SAMU, O FI OWO RA ORI O KAN TIRẸ WAYI O, IGIDA.

Agogo mejila abọ ọjọ Monday ijẹfa ni a ṣe alabapade Ọgbẹni Agbalagba kan ti o nba awọn ọkunrin Kalaba kan ati Awusa ta tẹtẹ, Ọgbẹni yi ta tẹtẹ titi o fi jẹ owo bi pọnwun meji ko lọ nigbati igba ma wa yipada fun Ọgbẹni yi nwọn gba gbogbo owo yi lọwọ rẹ tan ati tirẹ pẹlu ka wi ka fọ Ọgbẹni na bọ ẹwu fila on papa wa wa ni ihoriho, ni ero pe boya on yio tun jẹ owo on pada, ṣugbọn Ọgbẹni na mu ofo awọn onitẹtẹ fa owo ati ewu fila mọra, o wa ku ohun ti Baba ma fi bo aṣiri ararẹ lọ sile, ọgbẹni yọ ikun silẹ ondan gbinrin larin gbogbo ọmọ Anabi Adamọ, itiju ni on ko ran Baba nṣẹ ti o ba jẹ pe awọn ọmọde lo ṣe iru yi lọ ba Ọgbẹni yi ni ile nkọ o? Ọgbẹni yi ba wi fun pe ko kuro ninu ile tabi ko tete lọ wa ibi ti yio ma gbe, ẹ wa ri nkan wa bi! baba wa dorikodo on ronu Baba mu wọn lo ko owo ile rẹ yio ku ko fi gbiyanju, ṣe iwọ fẹ la ọla ojo ni, agbalagba tiko ninu rori ti o nba ọmọde ta tẹtẹ, ko ha tan na.

Mo duro nihin.

TẸNIMASUNWỌN.

---


### KERE O!

Mr. C. B. SHODIYA, *Produce Buyer*, ti No. 132, nitosi Niger Company, Ebute Ero, ni ọpọlọpọ Tapo (Tapaulin) siye 15 x 15 fun hihaya, bi o fẹ ṣe ariya ti Iyawo lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe Wolimọ lọ sibẹ, bi o fẹ ṣe ariya nipa ti oku lọ sibẹ, o wa fun ẹnikẹni ọpọku-ọyọku ni owo hihaya rẹ.

9d. ẹgbẹdogun fun Tapo kan lojumọ.

C. B. SHODIYA,<br>
*Produce Buyer*.<br>
132, Ebute Ero,<br>
Marina, Lagos.

# JUST ARRIVED.

The long expected Zotal, Glaxo, Lactogen, Vapex Kruschen Salts, Hair Dye, Kalzana, Vitafer, etc., etc.

### ***Ressurrection of the body.***

Do not remain a victim of chronic weakness, pains in the bones, shortness of breath, shaking of the hands and limbs. Get a bottle of Dr. de Roos concentrated Guittæ Vitæ, it will renew every atom of your flesh into activity and set you along the pathway of longevity. **£2 2s.** a bottle, largest size.

### ***If the blood is pure, health is sure.***

Our " Cooling Blood Purifier " purifies the blood of all impurities **7/6d per bottle.** Herb Tea—6d per packet. Native own remedy clears the bowels, purifies the blood.

### Why do experienced mothers like Yaro ?

Because it is a reliable preservative which suppresses infant's suffering during teething period. **2/3d & 3/3d** per bottle

### ***Life Tonic Tablet—A Wonder Worker.***

Life Tonic Tablet contains pure yeast and vitamines and can be taken by men with large or small means. It is a wonder worker. 3/- per bottle.

### ***Wireless Female Pills.***

For all monthly disturbances peculiar to females, use Wireless Female Pills, the latest scientific discovery for female disorders. **4/6d** per bottle. It is an effective fertiliser against barreness. Sold only by Iyin Oluwa Medicine Stores.

### WE STOCK:—

Back and Kidney Pills 2/6d
Anti-Rheumatic Salt 2/- & 3/6d
Vibrona Wine 7/6d.

*Obtainable at:—*

# IYIN OLUWA MEDICINE STORES

*Head Office* :—88, Broad Street, Lagos,
*Branches* :—6, Martins Street,
41, Alli Street, Faji Market,
109 Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki jẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS (10s) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian. Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B:- Not obtainable elsewhere.*

### GBOGI ONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ baję, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
Postage 2/6 extra.

WHITE'S

## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.
Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.
N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nfi iwe şişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*(A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy for Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ, *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rẹ mọ (lalai to aseko). nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbo, Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi, Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

---

### GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop. 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic : has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

---

*Cable Address* :—" WHITE LAGOS ".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.

---

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

---

## TO LET.

One Splendid Pleasure Car

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to —

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

## ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko,

—— : o : ——

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmini ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.


Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, and Published by Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lecturer.